# DIDÁ ENIYAN

### Gẹnẹsisi 1:26-31; 2:1-25

### ẸKỌ 2 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Titobi li OLUWA, O si ni iyìn pupọ̀-pupọ̀" (Orin Dafidi 145:3).**

**Awọn Olugbe Kin-in-ni ninu Ayé**

Ayé ti o dara ti wà ni imurasilẹ nisisiyii fun awọn olugbe rẹ̀. Ọlọrun ti dá ẹja, ẹyẹ ati awọn ẹranko, alaafia si wà ni ibi gbogbo. Ṣugbọn ko si ọkan ninu awọn ẹranko wọnyii ti yoo ṣe Ijọ Ọlọrun. Wọn ko ni oye ti wọn le fi sin Ọlọrun. Iṣẹ ti o tobi ju lọ ti o si kẹyin ninu didá ayé lo kàn nisisiyii, iṣẹ nla naa ni – didá eniyan ti yoo maa sin ti yoo si maa fi iyin fun Ọlọrun.

O dabi ẹni pe Ọlọrun n pe igbimọ kan nigba ti O wi pe, "Jẹ ki a dá enia li aworan wa, gẹgẹ bi irí wa." Ede Heberu ti a lò fun "Ọlọrun" ninu itan dida ohun gbogbo ni "Elohim" ti o duro fun nnkan ti o ju ẹyọ kan ṣoṣo lọ, o n sọ fun wa pe a le ri ju Ẹni kan lọ ninu Iwa-Ọlọrun, ati pe Ọlọrun Baba kò nikan wà.

Johannu Apọsteli sọ pe Jesu wà nibẹ ni atetekọṣe nigba ti Ọlọrun dá ayé. Johannu kọwe pe Jesu ni Ọrọ Ọlọrun, "Ọrọ na si di ara, on si mba wa gbé" (Johannu 1:14). "Nipasẹ̀ rẹ̀ li a ti da ohun gbogbo; lẹhin rẹ̀ a ko si da ohun kan ninu ohun ti a da" (Johannu 1:3). A si mọ pe Ẹmi Mimọ wà nibẹ pẹlu, nitori "Ẹmi Ọlọrun si nràbaba loju omi" (Gẹnẹsisi 1:2).

Nisisiyii Iwa-Ọlọrun -- Ọlọrun Baba, Ọlọrun Ọmọ ati Ọlọrun Ẹmi Mimọ́ -- fẹ dá eniyan - ki i ṣe lọna ti a gbà dá awọn ẹranko, ọkọọkan "ni irú tirẹ̀" ṣugbọn a dá eniyan ni aworan Ọlọrun, ati gẹgẹ bi iri Rẹ̀. Eniyan, ni ipilẹṣẹ ẹda rẹ̀ jẹ́ mimọ́ ati alai ni abawọn, o si fẹ ṣe ifẹ Ọlọrun. Oun ko ni ifẹ awọn ohun buburu, ko ni aisan ni ara, ko mọ ibanujẹ tabi itiju.

Ọkunrin yii ni yoo ṣe ipilẹṣẹ Ijọ Ọlọrun, Ọlọrun si fẹran rẹ̀. "Ẹ wo irú ifẹ ti Baba fi fẹ wa, ti a fi npè wa ni ọmọ Ọlọrun" (1 Johannu 3:1).

**Lati inu Erupẹ**

Erupẹ ilẹ ni Ọlọrun fi dá eniyan, awọn ẹlẹkọọ nipa ohun ẹlẹmi sọ fun wa pe wọn ni ohun mẹrindinlogun tabi ju bẹẹ lọ ti o wà ninu ara wa ninu ilẹ. Lẹyin ti idajọ iku ti wá sori eniyan, Ọlọrun wi fun Adamu pe, "Erupẹ sa ni iwọ, iwọ o si pada di erupẹ" (Gẹnesisi 3:19).

Ọlọrun dá eniyan ni aworan ara Rẹ̀, O si mi eemi iyè si inu iho imu rẹ̀; "enia si di alãye ọkàn." Bi o tilẹ jẹ pe ara n kú, o si n pada si erupẹ, ẹmi yoo wà laaye titi laelae. Yoo pada si ọdọ Ọlọrun ti o fi i fun ni (Oniwasu 12:7).

**Agbara lori Awọn Nnkan ti A Dá**

Eniyan ti a dá ni aworan Ọlọrun ni a fun ni agbara lori gbogbo ẹdá iyoku. Gbogbo ẹranko ni o wà labẹ akoso Adamu, wọn si gbọdọ gbọran si i lẹnu. Gbogbo igi ati eweko ni a dá fun ire rẹ̀.

Ọlọrun pe awọn ẹranko naa lati wá siwaju Adamu, ki o ba le sọ wọn ni orukọ. Ẹgbaagbeje awọn ẹranko ti Adamu sọ lorukọ ni wọn to lọwọọwọ, awọn bi kiniun, beari, ọ̀bọ, ẹṣin, ehoro ati ogunlọgọ awọn ẹranko miiran, ṣugbọn laaarin gbogbo wọn, ko ri alabagbe kan fun ara rẹ̀. Kò si ọkan ninu awọn ẹranko naa ti o dabi rẹ̀. A dá a ni àyè ti rẹ̀, ni ọ̀tọ̀ gedegbe.

Awọn ẹlẹkọ-ijinlẹ ati awọn ọjọgbọn nipa ohun ẹlẹmi kò ti i ri ohun kan lati fi idi ero-ori agbekalẹ ni pe eniyan jade wá lati inu ẹranko mulẹ. Lati ipilẹṣẹ ni Ọlọrun ti ṣe eniyan ni ẹ̀dá ti o yatọ patapata, ninu ọgbọ́n, ni pipé ati ni ẹwà. Nigba ti eniyan dẹṣẹ, o sọ pipé naa nù, ṣugbọn o ni òye ati agbára lati sin Ọlọrun sibẹ.

Ọlọrun ri i pe kò dara fun ọkunrin naa lati nikan wà, nitori naa O wi pe Oun yoo dá oluranlọwọ fun un. Ipinnu Ọlọrun ni pe ki ọkunrin naa ki o fẹran ẹni keji rẹ̀. O mu ki oorun ijika kun Adamu; O si dá obinrin lati inu egungun ihà ti O mu jade lẹgbẹ Adamu. Bayii ni obinrin naa fi jẹ́ apa kan ọkunrin tikara rẹ̀. Adamu wi pe: "Eyiyi li egungun ninu egungun mi, ati ẹran-ara ninu ẹran-ara mi: Obinrin li a o ma pè e, nitori ti a mu u jade lati ara ọkunrin wá."

Nigba ti iṣẹ didá ayé pari, Ọlọrun wò o, o si tẹ Ẹ lọrun. O wi pe "daradara ni."

**Igbeyawo Kin-in-ni**

Ninu Ọgbà Edẹni ni a kọ́ ti ṣe isin igbeyawo kin-in-ni, Ọlọrun tikara Rẹ̀ ni O si ṣe e. Ọlọrun ṣe ofin kan ni akoko naa. "Nitori na li ọkunrin yio ṣe ma fi baba on iya rẹ̀ silẹ, yio si fi ara mọ́ aya rẹ̀: nwọn o si di ara kan." Nigba ti Jesu n ṣe alaye nipa ọrọ naa, O fi kun un pe: "Nitorina nwọn ki iṣe meji mọ́ bikoṣe ara kan. Nitorina ohun ti Ọlọrun ba so ṣọkan, ki enia ki o máṣe ya wọn" (Matteu 19:6). Nitori naa ofin Ọlọrun ti o lodi si ikọsilẹ ati atungbe iyawo ti wa lati atetekọṣe, o si jẹ ọkan ninu ofin laelae ti Ọlọrun tete kọ ṣe.

Ọgba Edẹni ni ile Adamu ati Efa. Gbogbo ayé ni ibi ti o dara lati gbe, ṣugbọn Ọlọrun fẹran Adamu ati Efa to bẹẹ gẹẹ ti o ṣe ọgba pataki ti o lẹwa pupọ yii fun wọn. Oriṣiriṣi igi eleso ni o hù ninu ọgba yii fun wọn lati maa jẹ. Iṣẹ kan ṣoṣo ti a fun Adamu ni lati maa tọju awọn ohun ọgbin wọnyii, ati lati kó eso ti o ba fẹ lati jẹ jọ. Ko si pe ki o ṣẹṣẹ maa bu omi rin wọn nitori "ikũku a ti ilẹ wá, a si ma rin oju ilẹ gbogbo." Ojo ko rọ̀ lati ba ohun ọgbin jẹ́.

**Ifẹ n Fi Fun Ni**

Ọlọrun pese ohun gbogbo ti eniyan n fẹ́, O si fun un lọpọlọpọ si i fun igbadun rẹ̀. A, ifẹ Ọlọrun ti o ṣe gbogbo eyi fun eniyan!

**"Ifẹ n funni titi --**

**O n dariji –o si wà titi lae**

**O duro laelae**

**Pẹlu ọwọ ninà jade**

**Nigba ti o si wà sibẹ, O n funni**

**Nitori eyi ni ẹkọ Ifẹ --**

**Lati funni – funni – ati funni."**

**Igi Eewọ**

Awọn igi meji ti o yatọ si awọn igi iyoku wà ninu ọgba yii. Ọkan jẹ́ igi imọ̀ rere ati buburu, ekeji si jẹ́ igi iye. Ko si ofin ti o lodi si jijẹ eso igi iyè. A dá eniyan lati wà titi lae, oun ki ba si ti kú laelae bi o ba ṣe pe ko dẹṣẹ.

Ṣugbọn ninu eso igi ekeji, igi imọ rere ati buburu, Ọlọrun wi pe eniyan ko gbọdọ jẹ ẹ́. Eyi ni ohun kan ṣoṣo ti Ọlọrun kọ̀ fun wọn lati jẹ ninu Ọgbà Edẹni. Ko si si ofin miiran ti a fi fun Adamu ati Efa. Wọn le ṣe ohun ti o wù wọ́n lati gbadun ohun gbogbo ti Ọlọrun ti dá fun wọn.

Bayii ni igbesi-ayé bẹrẹ ninu ayé yii, ni alaafia ati irọra, ninu ẹwà iwa-mimọ́. Wo bi ipò ibukun yii ti logo to! Awọn ẹranko a maa jẹ ninu eso ajara, gẹgẹ bi eniyan ti n ṣe, ko si si pipa. Ko si ohun ti o le fo ni laya. Ọlọrun ti fi ibukun Rẹ̀ sori gbogbo ẹdá Rẹ̀, O si ti pe e ni daradara. Gbogbo iṣẹ ọwọ Ọlọrun ni o fi ifẹ ati agbára Rẹ̀ hàn.

**Iyawo Kristi**

A le ri apẹẹrẹ Iyawo Kristi ninu itan didá ayé. Gẹgẹ bi a ti mu egungun ihà kan jade lara Adamu lati fi dá obinrin, iyawo rẹ̀, bakan naa ni a o mu awọn ayanfẹ diẹ ti wọn ti mura silẹ, jade lati inu gbogbo ibi ti Isin Kristi dé lati ṣe Iyawo Kristi. Ki i ṣe gbogbo awọn ti o n wi pe, "Oluwa, Oluwa," ti wọn n ṣe bi ẹni pe wọn jẹ Onigbagbọ́ ni yoo lọ si Ọrun. Yoo jẹ iba awọn eniyan diẹ wọnni, nihin ati lọhun, yika gbogbo ayé, ti wọn n tẹle awọn ẹ̀kọ́ Jesu, ni yoo jẹ awọn ti O yàn. A gbọdọ jẹ oloootọ titi Jesu yoo fi dé, nigba naa ni Oun yoo mu wa lọ lati jẹ́ Iyawo Rẹ̀. Jesu wi pe, "Ẹniti o ba ṣẹgun li emi o fifun lati joko pẹlu mi lori itẹ́ mi, bi emi pẹlu ti ṣẹgun, ti mo si joko pẹlu Baba mi lori itẹ́ rẹ̀" (Ifihan 3:21). Lonii, Onigbagbọ́ aṣẹgun n duro lati gbọ́ ifilọ naa pe: "Igbeyawo Ọdọ-Agutan de, aya rẹ̀ si ti mura tan" (Ifihan 19:7).

## AWỌN IBEERE

1 Ta ni Ọlọrun n ba sọrọ nigba ti O wi pe, "Jẹ ki a dá enia li aworan wa"?

2 Bawo ni a ṣe mọ̀ pe Jesu wà nibẹ ni akoko didá ayé?

3 Ki ni sọ fun wa pe Ẹmi Mimọ́ wà nibẹ pẹlu?

4 Lati inu ki ni a ti dá eniyan?

5 Darukọ awọn ọna diẹ ti eniyan fi yatọ patapata si awọn ẹranko.

6 Nibo ni obinrin ti jade wá?

7 Ofin Ọlorun wo ni a fi fun ni ninu Ọgbà Edẹni nipa igbeyawo?

8 Ki ni Jesu wi nipa ofin igbeyawo?

9 Ibi pataki wo ni Ọlọrun fun Adamu ati Efa fun ile?

10 Ki ni aṣẹ kan ṣoṣo ti Ọlọrun fi fun wọn?